Yoruba

Ifojusona fun eto isuna nla
ti NESG fun Odun **2022**

THE NIGERIAN ECONOMIC SUMMIT GROUP

# Ona Abayo Ikehin:

## Atunse lati mu idagbasoke ba abajade eto isuna gbogboogbò



## 1.0 TITO AAYE YII

Orile ede Naijiria tin lo awon ilana ti yoo mu ipadabo sípò baa nibi ipada séyìn eto isuna eleyii ti arun Korona múwá, sugbon àìse deedee eleyii to ti ba eto isuna nla saaju ìtànkálè arun naa si tun be nle.

Bo tile je pe o ri idagbasoke to to ida meta o le meji (3.2%) ninu ida ogorun ni ida meta akoko odun 2021, eri fihan lati owo ajo National Bureau of Statistics (NBS) wipe idaji iye oja ati ise lo gbénu soke, àìse deedee o yee ba isowo lokan-o-jòkan, bee sini ìdádúró ba wíwọlé idasile awon ile-ise okere. Banki agbaye ti se isiro wipe milionu mejo awon omo orile-ede Naijiria ni osi nba fínra laarin odun 2020 ati 2021 latari ìfàsẹ́hìn to ba oja rira. Bo tile je pe orile-ede Naijiria si ni okan-o-jòkan afojusun, ìfàsẹ́hìn o yee ba pipese ise laarin awon eka lórísìírísìí eleyii to nmu àlékún ba airi ise se awon eniyan.

Bi a se nri àlékún to jojú ni awon àgbónni kan, gege bi si sètò ipawo wole lati ona eleyii to yato si epo-robi bi odun die seyin, nkan kan lo daju: Orile-ede Naijiria o le tesiwaju nibi ona sise ofin-in-re pelu isowo eleyii ti a mo. Igbega to nba aisi eto abo ati awon iwa buruku lawujo ni orisiirisii aaye ni orile ede yii je eri wipe ti ìfàsẹ́hìn ba ti ba awon olugbe agbegbe kan, yoo mu aisedeede ba awon ànfàani ti o wa nile saaju àjàkálè arun Korona, yoo si tun dènà awon idasile olókan-o-jòkan ti yoo mu orile-ede yii tesiwaju.

Awon ipenija ti o niise pelu aisi eto abo, owon gogo iye oja, airi ise se, ati ìfàsẹ́hìn nibi ida ile ise sile je idi gbòógì ti a fi gbodo wa ona abayo eleyii ti yoo mu oro aje orile-ede yii ru gogo si, ti yoo si mu ìdàgbàsókè ba lawujo. Eleyii o je ki awon owo ati eeyan lòrísìírísìí je okan gbogi ninu sise ofin and ati àlàkalè ijoba.

Lótìtóó, awon ipenija to kojú orile-ede yii o kere. Sibesibe, odun 2022 mu awon anfani ti o legbe wa fun orile-ede Naijiria lati bere awon ilana ijiroro to munadoko ti yo mu oro aje orile-ede dagba ti yoo si mu pe dáadáa. Ni odun 2022, ijiroro ti o jọjú gbodo wa fun awon oro tipe tipé lori aibowo fofin, owon pàsípààrọ̀ pelu ile okeere ati ifasehin ninu idasile laarin awon eka tose koko julo. Fun apere, ijiroro nipa aibowo fofin ni eka to nrisi epo robi ati afefe gaasi je ohun ti a gbodo mojuto ni iru akoko yii ti a nilo idasile olokan-o-jokan lati se atunse si ipo buruku ti awon ile-ise ibi iyopo ti a ni. Eleyii o yo orile-ede yii kuro nibi mimo gbe epo robi lo si orile-ede okere fun yiyo eyi tin ko ifasehin nla ba nibi sis'amojuto awon nkan Pataki miran. Bi iwe ofin Petroleum Industry Act (PIA) fi idi awon ofin to ti pe yii mule, o di dandan lati sa ipa lati mu idagbasoke ba eka yii lati baa mu koriya wa fun awon oluda ile ise sile ninu oro aje ile Naijiria

Ko si aniani wipe sise awon atunse wonyii a na ijoba, awon ile-ise ati eniyan lowo. Sugbon, ise nla to wa niwaju ijoba ni wipe kiwon o wa ripe iye ti yoo nawon ja wa le lati lee mu anfaani nla wa fun awon alakoso eleyii ti yoo si sokunfa idagbasoke fun orile-ede lona ati gbega. Ninu daadaa ti o tin je jade lori eto yii ni ifi lole National Development Plan (2021-2025) ti o fi ilana ati afojusun eleyii ti won o samulo ni odun maarun si isiyin. Sibe sibe naa, aseyori ilana yii wa lowo isamulo ati eto iru eyi ti awon igbimo ijoba lorisiirisii ba nse,

mimu awon ilana naa wo ese kuku lati odo ijoba ipinle ati awon eka ifokansin awon aladani lati se idasile awon idoko owo to se koko ni eka oro aje. Eyi to se koko julo nipe ki ijoba je asiwaju ninu sise agbegbeewa ni eyi ti o mu idoko owo rorun, ki won o si se ifese rinle to muna doko fun eto oro aje nla ati sise koriya fun idoko wo kaakiri eka.

Pelu odun kan to ku lori ipo, ijoba to wa lori ase yii gbodo salekun isatunse, paapaa julo nibamu si awon ipenije elega meji osi ati airisese eleyii ti o wa lori aisi eto abo ati awon idarudapo lawujo. Lati mu ojo iwaju Naijiria dara, ijoba gbodo sise to awon nkan yii ni waransesa. Eto isuna ati atunse si awon eka lawujo ti yoo mu ipese ise yapa ti yoo si se alekun daadaa fun awon omo orile-ede Naijiria o tun gbodo je ohun ti ao mo je atare-e-re ni odun 2022.



## 2.0 APA A: ETO ISUNA NAIJRIA NI ODUN 2022 ATI AFOJUSUN FUN ODUN 2022

Apa yii ko agbeyewo awon ohun eto isuna odun 2021 sinu, bakan naaa ni o tun ko awon ohun ti yoo mu eto isuna ti gira ni odun 2022 ati awon afojusun fun odun naa. Agbeyewo eto isuna orile-ede Naijiria ko nkan merin sinu—idagbasoke eka ile-ise, isamulo ibagbepo ati isamulo inawo, isamulo owonaa ati ifi ofin to to dee pelu awon eka miran.

Awon Koko Agbeyewo Eto Isuna Orile-ede Naijiria ni odun 2021

- Eto isuna ile Naijiria fi ese igbabosipo rinle ni odun 2021. Apapo owo to nwole fun ijoba lo soke si pelu ida meji o le die (3.2%) ninu ida ogorun ni idameta akoko odun 2021 ni afiweere pelu asiko kan naa ni odun 2020.

- Ikobiara si awon ise awon eka lorisiirisii nse fi han wipe opolopo awon eka to nri si ise sise lo ri idagbasoke to joju pelu owo to nwole si apo won laarin osu kinni si osun kesan odun 2021.

- Awon afikun orisiirisii si ja wa le gan lati idakeji ninu idameta odun 2021. O si ku si ida metadinlogun (17.0%) ninu ida ogorun lapapo ni odun 2021.

- Idiwo si tun wa fun owo nina pelu bi owo epo si tun se gbera soke koja aala alakale isuna fun odun 2021 naa.

- Nitori aipe ojuwon to lagbara to nba inawo, yiya owo ile Naijiria ti gbenu soke si. Gege bi ofiisi to nri si isakoso gbese (Debt Management Office) ti so, apapo gbese ile Naijiria ni deedee osu kesan odun 2021 gbenu soke pelu N38 trillion, eleyii to je alekun ida meedogun o le maarun (15.5%) ninu ida ogorun laarin osu mesan.

- Koda yato si igbenusoke to nba gbese yii, ifesemule Naijiria pelu iye gbese yii je ohun to nko ni lominu

- Eka to nrisi isamulo owonaa se eto isamulo idagbasoke ni odun 2021.

- Ni odun 2021, ipo ile Naijiria ni okeere paapaa julo nibi idoko owo oja tita tun ja wa sile. Bo ti le je pe alekun to to ida ogoji (40%) ba tita ojaa sita, apapo owo ile Naijiria nibi owo sise tun buru jai.

- Bi aburu ti arun Korona se eto isuna orile-ede Naijiria si se tun wa anile, orile-ede yii tun beere fun owo yiya lori awon ohun to ni nile okeere ati lori pàsípààrọ̀ owo.

## 2.1 AFOJUSUN WA FUN ETO ISUNA ILE NAIJIRIA NI ODUN 2022

A daba isele meta to seese fun abajade eto isuna ni odun 2022.

- Isele Isowo bii ti Tele (1) eleyii da lori ero ise dogba-n-dogba wipe majemu eto isuna nla si tun wa gege bi ti odun to siwaju ati awon erongba to yi Appropriation Act ti odun 2022 ka.

- Isele Eleyii to Dara ju (2) eleyii rora je eyi to da lori inireti gege bi "isele isowo bii ti tele." Won mo iye owo epo robi lori idaji ojo iwaju epo robi New York Mercantile Exchange (NYMEX) fun osun kinni ssi osu kewaa odun 2022.

- Isel Eleyii to Buru ju (3) eleyii rora je eyi to mu irewesi okan dani gege bi "isele isowo bii ti tele."

| | Ero | Abajade | Afokansi |
|---|---|---|---|
| **Isele Akoko: Isowo bii ti Tele** | Idaji owo epo robi je US$62 fun jala kan (pb); idaji sise epo robi je jala lona milionu 1.66 fun ojo kan (mbpd); owo nina si ku si ₦3.5 trillion. | Owo to nwole po si pelu ida meji le meje (2.7%) ninu ida ogorun; idaaji afikun iye oja je ida meeedogun (15%); owo ti nwole fun ijoba ri alekun ida ogun (20%), ipàṣípààrọ̀ owo ti o bofin mu gbénu wale, o si tun fese rinle pelu ₦430/US$1; iye ipasipaaaro ti o bofinmu si je ₦550/US$1; iye airi ise se je ida meta-le-logbon (33%); iye aigbani sise si je ida mokandinlogbon (29%). | Iye ti o je nina jade lekun si pelu ida maarun (5%); gbese ijoba si lekun si pelu ida mokanlaa (11%). |
| **Ise Eleekeji: Eleyii to dara ju** | Idaji owo epo robi je US$75 fun jala kan; idaaji sise epo robi je jala lona milionu 2.0; owo nina si ku si ₦4.05 trillion. | Owo to nwole po si pelu ida meta o le meji (3.2%); afikun iye oja bo si deedee pelu ida mejila (12%); owo ti nwole fun ijoba ri alekun ida ogbon (30%); iye ipàṣípààrọ̀ owo ti o bofin mu fe se rinle si ₦415/US$1; iye ipàṣípààrọ̀ ti o bofin mu si je ₦535/US$1; iye airi ise se je ida ogbon (30%); iye aigbani sise si je ida mejilelogun (22%). | Iye ti o je nina jade lekun si pelu ida mesan (9%); gbese ijoba si lekun si pelu ida mesan (9%). |
| **Isele Keta: Eleyii to buru ju** | Idaji owo epo robi je US$50 fun jala kan; idaji sise epo robi je jala kan o le meji (1.2) lojumo; owo nina si ku ₦2.7 trillion | Owo to nwole po si pelu ida kan o le mejo (1.8); afikun iye oja lekun si ida metadinlogun (17%); owo ti nwole fun ijoba ri adinku ida ogun (20%); iye ipàṣípààrọ̀ owo to bofin mu fa seyin si ₦450/US$1; iye ipàṣípààrọ̀ ti o bofin mu si je ₦600/US$1; iye airi ise se je ida ogoji (40%); iye aigbani sise si je ida mejilelogbon (32%). | Iye ti o je nina jade lekun si pelu ida meta o le maarun (3.5%); gbese ijoba si lekun si pelu ida mokandinlogun (19%). |

Figure 1: Iye ati Afojusun Idagbasoke Owo ti Yoo Wole ni Odun 2022



## 3.0 APA B – ONA ABAYO IKEHIN: ATUNSE LATI MU IDAGBASOKE BA ABAJADE ETO ISUNA GBOGBOOGBÒ

Apa yii salaye awon ohun ti o ni base pelu akori iwe aabo yii – Ona Abayo Ikehin: Atunse lati mu idagbasoke ba abajade eto isuna gbogboogbò. Nkan meta gboogi ni a mu enu ba, awon naa ni Gbigbe awon ilana kan kuro ni Eka Epo Robi ati Afefe Gaasi ati Atunse si Owo Ìrànwǒ Ori Epo, Atunse si Ipàsípààrọ̀ Owo Pelu awon Ile Okeere ati Atunse si Awon Eka Lapapo

## A. GBIGBE AWON ILANA KAN KURO NI EKA EPO ROBI ATI AFEFE GAASI ATI ATUNSE SI OWO ÌRÀNWǑ ORI EPO

Lati igbati ijoba awa araawa ti pada de orile ede Naijiria ni odun 1999 ni oro ti nwaye lori gbigbe awon ilana kan kuro patapata lori oro epo robi ati afefe gaasi ati yiyo owo ìrànwǒ kuro lori epo. Bo ti le je pe owo ti ijoba ile Naijiria nri lati ibi epo robi ati afefe gaasi ninu apapo owo ti nwole ko ida merin-le-logbon (34.9%) to si ko ida marun-din-laadorun (85.2%) ohun ti a nko jade lo si okere, ile-ise yii si tun lakaka pelu ilowosi eleyii to mehe si owo to nwole fun orile-ede (pelu ida mejo le eyokan—8.1%) ni idameta akoko odun 2021 (NBS; FMFBNP; 2021).

Gege bi ona lati mu eka yi gbera soke, ofin tuntun ti Petroleum Industry Act [1](PIA) ti odun 2021 ti won sese se ko awon orisiirisii atunse sinu. Lati waa je daadaa ninu anfaani PIA yii, o se Pataki ki a mu awon ilanaare lo daadaa. Pataki julo, ireti wa pe awon atunse ti PIA yii se idasile won yoo mu alekun bai da ile-ise sile si, yoo mu ise deedee ati iwulo po si, yoo si mu alekun to peye ba abajade ti o je mo sisamulo ile-ise epo robi ati afefe gaasi.

Ni afikun si gbigbe awon ofin kan kuro patapata lori ero epo robi, lara awon oro tin fa ariyan-jiyan ni eka naa ni sise atunse owo ìrànwó ori epo. Eleyii wa lara ipinnu to lagbara ti ile Naijiria ni laati se ni odun 2022. Owo ìrànwǒ ori epo, eleyii ti a mo si ona ìrànwǒ kukuru kan, ti wan le tipe tipe eleyii to sin je idunkoko fun eto owo nina. Laarin ogbon odun seyin, owo nla ninu owo ijoba ni ile Naijiria na lori iyowo ìrànwǒ, eleyii ti ai le mo ju too re sin gbelekee si. Koda, awon igara orisiirisii lori owo ara-ilu to njeyo lati ibi iyowo ìrànwǒ ori epo ti mu ijoba maa se atunse owo epo ni gbogbo igba. Sugbon o, gbigbe awon ofin kan kuro – eleyii ti a mo si ilana sise owo epo ni regi – kan npese iderun fun igba die ni nitori pe owo ìrànwǒ ori epo o tun wura si bi owo epo lagba'ye naa ba ti gbenu s'oke,

Awon ohun gbogi t'oye ki a ye saaju lilo ilana atunse yii lo wa ni isale yii:

- Ipa Afikun
- Ise deedee ni bi inawo ijoba
- Gbigbe s'oke eka epo robi ati afefe gaasi nigbati ijoba yoo mo ko ipa alase agba.
- Dida ile-ise sile ni agbonni isale ati aarin ile-ise epo robi ati afefe gaasi.
- Ilana ibara eni soro eleyii to peye

[1]Ise ti ofin Petroleum Industry Act (PIA) ti odun 2021 fee se ni atunse si ile-ise epo robi ati afefe gaasi ile Naijiria. Abadofin to ti waa di ofin PIA bayii ni won fi sowo si ile igbimo asofin aggbaa keji ni osu keje odun 2021, ti Aare Buhari si bu'wo lu ni osu kejo odun 2021. Ni ibamu si eda ofin naa eleyi ti won gbe jade, ijoba PIA bere ni ojo kerin-din-logun osu kejo odun 2021. Ofin naa fee gbe ona tuntun kale fun eka epo robi ati afefe gaaasi orile-ede yii. Awon wonyii ega maaarun ti PIA naa ko si'nu: 1, Isejoba ati Ile-ise, 2. Isakoso, 3. Idagbaso'ke agbegbeewa, 4. Inawo ni ile-ise epo bentiroolu, 5. Ilana ati awin nkan miran lo se koko.

Ni ikehin, iwe aabo yii daba awon koko won yii gege bi ona to dara ju lati fun sise atunse lori eka epo robi ati afefe gaasi:

- Mi mu yiyo owo ìrànwǒ ori epo ni die die.
- Sise amulo ilowosi awon ara ilu saaju gbigbe ilana iyowo ìrànwǒ dide lati le je ki won o ni igbagbo loriire.
- Sise atubse si idibaje ati aise deedee to w ani eka epo robi ati afefe gaasi.
- Sisa ipa si lati le mu idagbasoke ba ipawo wo'le.

## B. ATUNSE SI IPÀSÍPÀÀRỌ OWO PELU AWON ILE OKEERE

Awon ipenija to nkoju is'akoso ipàsípààrọ owo pelu awon ile okeere ni ti wa tipe tipe. Awon agba bo won ni "eni ti yoo daso fun ni, t'orun e laakoo wo." O ye ka mo pe igbarale kiko nkan wole lat'okeere ti mu ki orun wo awon ifipamo ti orile-ede yii ni ni'ta ati ipàsípààrọ owo. Ajo National Bureau of Statistics (NBS) so wipe, ida mokan-le-logota ni iko oja w'olee nikan ko ninu gbogbo ida isowo pelu awon ile okeere ni odun 2020. Ki a to mu enu ba awon oro to nii base pelu wiwa ati iyw owo pàsípààrọ owo pelu ile okeere, o se Pataki ki a s'are se amujuto ifasehin nibi abajade awon ile-ise ti o kin se tie po robi pelu afojusun to po lori pipa owo w'ole lati ibi pàsípààrọ owo pelu ile okeere.

Nibayii, gbigb'ara le nkan tin won ko w'ole lat'okeere ti fa idiwo fun banki apapo lori riri anfaaani fun ijiroro lori ipàsípààrọ lagb'aye lati odun 2015 lati s'eto toye lori ibeere fun pasipaaaro owo pelu ile okeere ati lati fa'gile awon oja kookan, awon eleyii ti a le maa pese ni labele. Esi ilana yii ti mu alekun ba ibeere awon eniyan ni oja ifi-owo-ropo, eleyii to nfa aala nla laarin iye pàsípààrọ owo ti ijoba (eleyii ti a mo si I & E Window exchange rate) ati iye pàsípààrọ eyi ti o kin se ti joba (wo Fig. 4f ni apa A).

Awon ipenija to nba ile Naijiria ni bi pàsípààrọ owo ni a le se afitiire si aise amulo orisiirisii ona pàsípààrọ pelu igbarale to ti poju lori epo robi ati l'enu lowo yii yiya owo lati ile okeere. Ipenija miran ti o tun koju sise amojuto pàsípààrọ owo ni ile Naijiria dida si gbogbo igba eleyii ti banki apapo ile yii ndaa si oja pàsípààrọ owo eleyi ti nko ipalara pupo ba awon ohun ti orile-ede yii ni l'okeere. Pelu jija wa'le iye ohun ti orile-ede yii ni l'okeere, banki to gaju naa tun ti fabo si sise adinku iye owo ipàsípààrọ (isele iru e meta ni a ri ni odun 2020) ati fifi odiwon si iye ti awon eeyan le paaro. Awon ipenija yii lo ko di awon to fee fo wo sowo nipa aabo isowo-o-won (paapaa julo dida owo pada si orile-ede ti won I paaroore ni afinkun si awon isakole ti o wa nibe).

**Atunse Akoko: Idi lati S'agbega Pipo Ilana Pàsípààrọ Owo Pelu Ile Okeere**

- Lilo ajo African Continental Free Trade Area (AfCFTA) ati sise amojuto to peye si eto enu ibode.
- Yiyo awon ofin inawo kuro ati sise koriya fun idoko'wo to fe'se mule.
- Titi pàsípààrọ owo eyi to njade lati eka to yato si eka epo robi siwaju.
- Sise iranlowo fun didara awon ohun ti a fin ropo awon ohun ti a nko wole.
- Sise atunse awon ile-ise ifopo abele ati dida titun sile.

**Atunse Eleekeeji: Idi Lati Samulo Iye to Dara fun Pàsípààrọ̀ Owo Pelu Ile Okeere**

- Ilana to han kedere lorii pàsípààrọ̀ owo eleyii ti yoo fokan awon oludoko'wo bale.
- Idi lati mo iye to peye fun owo Naira.
- Sis'amulo ilana irorun to jindo ni agbonni pàsípààrọ̀ owo.
- Ilana ofin to peye fun dida sii banki apapo ni agbonni pàsípààrọ̀ owo.
- Ilana toye miran lati paaro iye ti won f'enu ko si nibi ilana pàsípààrọ̀ owo.
- Eto t'oye fun sise agbeyewo ati sis'akoso ile-ise ijoba ati ti aladani lo ri ewu to wa nibi pàsípààrọ̀ owo.

## C. ATUNSE SI AWON EKA LAPAPO

Bi o se je wipe idaji idagbasoke t'oto ida meta lee meji (3.2) lo baa ni idameta akoko odun 2021, eto isuna ile Naijiria koye-kogbo lati moo ri ija igbenus'oke, alekun l'ori airisese ati aigbani sise ati alekun osi ti nta awon eniyan. Awon ipenija yii si tun wa latarii aisi ilana toto fun idagbas'oke, pelu idagbas'oke to nba awon eka kan lasan eleyii ti ko si ni agbara lati le pese ise to nitumo fun awon eniyan.

A ni lati wa ona abayo si awon isoro to nkoju eto isuna ati biba ara eni se gege bi ifasehin to nba ipese ise, airi ise se, ai duro deedee ipàsípààrọ̀ owo lokeere, ifashein idoko'wo lokeere ati idiwo nibi ipawo wole fun ijoba ati aisi aabo to peye ni fun awon eka eto isuna lati tesiwaju ki won o se ko ipa to joju kaakiri. Koda, idagbos'oke awon eka to se koko julo naa tun ti jaw'ale si bo tiwa bi ipadasehin eleyii to waye saaju odun 2016 ni akoko ti oro aje orile-ede ru gogo daadaa ni odun 2014. Pelu ileri ijoba lati mu eeyan milionu maarun-din-logoji kuro ninu osi pelu pip'ese ise to peye ona milionu mokan-le-logun titi odun 2025, o wa leto fun ijoba lati se akoyawo to peye si awon eka eto isuna.

Bi ile Naijiria se ngbiyan ju ti o sin tan ise siseere ka awon eka eto oro aje lolokan-o-jokan, ijoba ni lati gbe ola fun awon eka lodiwon bi won se wulo fun oro aje si, ati si awon eka oro aje miiran ati eka ipese ise. Fun idi eyi, a toka si ilana atunse si eka Pataki maarun eleyii ti ijoba lee samulo lati je ki idagbas'oke o ba abaajade eto oro aje orile-ede yii. Awon eka wonyii ni Eka Eto Ogbin, Eka Ipese Ero, Eka Ilera, Eka Eto Eko, ati Eka Isowo. A ni igbagbo wipe awon atunse wonyii o mu alekun to ni itumo baa won eka yii ti yoo si mu idagbas'oke ba oro aje eyii to ko tol'ori tel'emu sinu.

## About The NESG

The NESG is an independent, non-partisan, non-sectarian organization, committed to fostering open and continuous dialogue on Nigeria's economic development. The NESG strives to forge a mutual understanding between leaders of thought so as to explore, discover and support initiatives directed at improving Nigeria's economic policies, institutions and management.
Our views and positions on issues are disseminated through electronic and print media, seminars, public lectures, policy dialogues, workshops, specific high level interactive public-private sessions and special presentations to the executive and legislative arms of government.

**Copyright © 2022**
**by the Nigerian Economic Summit Group**

All rights reserved. No part of this publication may be reproduced, stored in a retrieval system or transmitted, in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, or otherwise without the prior permission of the Nigerian Economic Summit Group.

---

For additional information with respect to this Report, please contact the following:

NESG Research & Development
research@nesgroup.org

---

**NESG DIRECTORS**

- Mr. Asue Ighodalo — Chairman
- Mr Niyi Yusuf — Vice-Chairman
- Mr Osagie Okunbor — Vice-Chairman
- Mr 'Laoye Jaiyeola — CEO
- Mr Yinka Sanni — Member
- Mrs Wonuola Adetayo — Member
- Mr Kunle Elebute — Member
- Mr Foluso Philips — Member
- Mr Udeme Ufot — Member
- Mr Olusegun Ogunsanya — Member
- Mrs Juliet Ehimuan — Member
- Mr Frank Aigbogun — Member
- Dr Philip Mshelbila — Member
- Mr Wassim Elhusseini — Member
- Mr Kyari Bukar — Member
- Mrs Amina Maina — Member
- Mr Nnanna Ude — Member
- Mr Karl Toriola — Member
- Mr Oluboyede Olusanya — Member
- Mrs Ndidi Nwuneli — Member
- Mr Mike Sangster — Member
- Mr Lanre Akinbo — Member
- Mr Demola Sogunle — Alternate

---

**Contributors**

- Dr. Olusegun Omisakin
- Wilson Erumebor
- Yinka Iyinolakan
- Faith Iyoha
- Shakirudeen Taiwo
- Sodik Olofin
- Dr. Oluwaseyi Vincent
- Wasiu Adekunle
- Henry Egbe

NESG

**THE SUMMIT HOUSE**
6, Oba Elegushi Street,
Off Oba Adeyinka Oyekan Avenue,
Ikoyi, Lagos.
P.M.B 71347, Victoria Island, Lagos

**ABUJA LIAISON OFFICE**
4th Floor, Unity Bank Tower,
Beside Reinsurnace building
Plot 785, Herbert Macaulay Way,
Central Business District, Abuja

www.nesgroup.org
info@nesgroup.org
+234-01-295 2849

officialNESG